28 FEB 1966


# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,693 WEDNESDAY, FEBRUARY 9 1966 (2D)


## Olosa kan w'ewon odun meji abo

JOS Ni opin ose to koja lo yi ni Adajo Kotu Ijoba Ibile ti Mkoli ti ilu Jos pase pe ki okunrin odaran Ilefole kan, Okoye Achama eni odun ne elogun yara lo fi ewon odun meji abo jura lori esun Ilefole ati ole jija eyiti awon olopa to ba odaran na se ejo fi kan olosa na pe Okoye Achama lo fo ile obinrin kan eyiti o fi ji awon eru kan lo ninu ile na.

Ninu oro olopa to ba odaran na se ejo ni o ti se alaye fun Kotu Ijoba Ibile na pe Okoye Achama lo fo ile Obinrin kan ti nwon ape ni Ladi Mai go ati pe olosa na si ji ibusun kan ti ise "Vono bed" ati irori eyiti iye owo won si je pounun marun (£5).

Ninu ile ejo na ni Adajo Kotu na ti pase pe ki awon okunrin meji kan Deso Jos ati Daneis Jos yara lo fi ewon osu meta-meta lo jura lori pe awon enia na jebi pe nwon gba eru ole sinu ile.

Adajo Kotu na tun pase pe ki obinrin kan Jima Jos yara lo fi pounun mewa tanra lori pe obinrin na ba awon okunrin meji na gba eru ole sinu ile. Adajo kotu na tun pase pe ki odaran obinrin na yara lo si ewon osu kan ti ko ba le ri pounun mewa (£10) lati fi tanra esun na. Sugbon Adajo si se alaye ninu idajo re pe awon enia meta yoku jebi esun na ati pe ki nwon si fi ewon lo jura.

# AWON OSISE FE KI IJOBA DIN OWO ILE KU

KADUNA:— Gbogbo ile lo kunsoso ti ese ko si gbero fun ogunlogo okeimoye awon enia ti nwon wa si ibi Ipade ti awon osise se ni ana ojo Isegun ti ise ojo keje osu yi nigbati awon osise na nse ipade lori eto wipe ki Ijoba le din owo ile gbigbe ku fun gbogbo awon osise yika Orile ede yi ati paapajulo, awon enia ti nwon gbe ilu Eko.

Okan ninu awon osise na so wipe, awon ti setan nisisiyi lati so fun Ijoba ni gbogbo orile ede yi wipe ki nwon jowo ki nwon ba awon din owo ile gbigbe ku fun awon osise.

Agbenuso awon osise na tun so wipe bi awon enia ba fe gba ile lati maa gbe awon onile yio so wipe ki nwon lo mu owo asan sile osu mefa wa si awon to ile fun won ni ile.

O tun so pelu wipe, bi nwon ko ba fun awon Onile na ni owo asansile osu meta tabi mejo, nwon ko ni gbe ile won fun awon osise, boyowu ki nwon le sa je si won, kodi bi won se omo ebi kanna, bi ko ba le san owo asan sile nwon ko ni gbe ile fun un.

O tun so siwaju ninu oro re wipe awon oni le miran ti lero pe ni sisiyi wipe awon ko tun gba owo osu mefa ni owo asansile mo a fi owo osu mejo ti awon nfe ni ti ripe awon (Onile) alle owo

Awon enia na so ninu Ipade wipe, awon nfe ki Ijoba Olo un yi tete yara ba awon mojuto eto owo ile gbigbe na kiakia

Nwon tun so pelu wipe, awon orile ede miran ti nse nisisiyi wipe, awon nfe lati maa gba pounun meje (£7) fun iyara kansoso ni Eko awon miran si nso wipe awon yio gba pounun mejo (£8) fun iyara kansoso.

Nwon ni awon osise miran ko tile ko lati gba ile na ni pounun mejo, sugbon nigbati awon onile na ba so wipe ki nwon lo mu owo osu mejo wa ni awon enia enia na ko ba tun le gba ile na mo.

Awon enia na wi ke si Ijoba Ologun Agu iyi Ironsi wipe ki o jo wo ki o gba awon osise kale lowo won oni le won yi ki nwon yo maa gbe ile won fun awon osise ni owo si ga ki Ijoba si pase wi pe ki awon ma gba ile fun won ni iye ti yio je iyekanna fun gbo— gbo enia yika Orile ede Naijiria ti awon onile kan ko ni yeju si ti awon elomiran.

Awon enia na so wi pe awon yio daa ni imoran bi Ijoba ba le pa ni ase wipe ki, ise owo Iyara kan ni Eko ma se ju pounun kan abo si po un meji (£1 10s si £2) lo ni iyara na tile ukioto

Nwon tun so pelu wipe, ki Ijoba tun pa ni ase wipe, ki iye owo awon osise ti won ngbe ile adagbe (Flat) ma se ju pounun mewa (£10) pere lo bi ile na tile si o tobi to,

Okan ninu awon osise na so wipe, Ijoba ase yori nigbana ba ana ti fe se eto nipa ati din owo ile gbigbe ku ni Eko, sugbon nwon ko le se eto na nitoripe opolo po ninu awon Minista igbana ni nwon ni ile ti nwon ko si fe ki

Ijoba se eto na ni Sugbon nisisiyi ti awon Minista ti ko gba won sile, nwon wa ro Ogagun Aguiyi Ironsi wi e ki o tete yara ba ewon mojuto

Awon osise na tun se alaye wipe, awon Onile ni nwon ko fi okan awon osise bale ti nwon ko si jeki won ri ile gbe ki ise ni ilu Eko nikan sugbon yi ka gbogbo Orile ede Naijiria ni,

WO OJU EWE KEFA

# Ha! Akintola Si Ku !!



OGBOMOSHO:- Irohin ko to afojuba ni ti Oloye Samuel Ladoke Akintola, Are Onakakanfo, eniti o ti fi igbakan je Alakoso Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria nigbati awon Soja gbe oku re wo inu ilu Ogbomosho ninu ose ti o koja lo yi.

Irohin fi ye wa wipe nigbati o ti di ose kan ti Oloye na ti ku, ni awon Soja to gbe oku re na kuro ninu ile Iwosan Lakulaku Ibadan ti nwon si gbe Oku re lo si ile re ni Ogbomosho

Aworan ti e nwo loke Iwe yi ni ti inu ogba ti nwon sin oku Oloye Akintola si ni ojo na,

# EGBE ỌDỌ AFẸNIFẸRE MUSHIN GBAYI O GB'ẸYẸ

MUSHIN:—:— Ọjọ nla ni ọjọ Aiku ti iṣe ọgbọnjọ oṣu to k ja lọ yi fun gbogbo ẹgbẹ ọdọ ni Mushin ti ẹgbẹgbẹ re at pa pa ul fun egbẹ odo ti Afẹnifẹre ẹka Fagbilẹ eyiti iṣe Ward 8, Mushin nigbati awọn ẹgbẹ ọdọ ni nṣe iveye si! Basikulu kan ti a npe ni Keleigh eyiti awọn egbẹ ọdọ na ṣeṣe ra lati ma lo fun eto igbokegbodo ẹgbẹ ọjọ Afẹnifẹre ẹka Fagbilẹ Mushin eyiti yọ jẹ ẹka ẹgbẹ ọdọ akọkọ ti yio ṣe iru ayẹyẹ bayi ni ẹkun Mushin ati agbegbe rẹ.

Ki ayeye eyẹ ọjọ na to bẹrẹ i dorde aguro mita ọsan ... awọn enia ja kanjankan nina awọn Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Eko, Ikẹja, Shomolu Agege, Isinẹ, Oshodi ati awọn ilu miran ni agbegbe ilu Eko ti nde sibi ayẹyẹ ọjọ na pelu ayọ eyiti o jẹ pe idunnu ṣubu lu ayọ ni ọjọ na fun awọn ẹka Afẹnifẹre Ikẹja ati lobi nina ti o wa sibi ayẹyẹ ọjọ na.

Nigbati ayẹyẹ ọjọ na bẹrẹ ni Akọwe eto akoso ẹgbẹ na Ọgbẹni K O San ... ni diẹ ti ṣe eto ... Alaga ayẹyẹ ọjọ na eyiti iṣe ọdọ ... kan ti o si tun jẹ ... eto ẹka Ọgbẹni J. A. Shọjupe ati Alaga Obinrin Iyaafin Nimọta Erufolahan ... awọn ọkọ ... ayẹyẹ ọjọ to wa sibi ayẹyẹ ọjọ na.

Lẹhin ... awọn Alaga Ọkunrin ati Alaga Obinrin han ni o tun ... ọkọ moye nwọn b Ọgbẹni A Agunbiade, Ọgbẹni O ... lọ, ... ati awọn ... wa sibi ayẹyẹ ọjọ.

Ninu ọrọ Alaga ọjọ na ni Ọgbẹni J. A. Shọjupe tun ... awọn ... ayẹyẹ ọjọ na ... pa pa julọ awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre pe ... awọn ... ti ... ti wa gbogbo awọn ... awọn Orile ... nigba ti awọn ọmọ ogun ilẹ Nijiria gba eto akoso ijọba ilẹ Naijiria bayi.

Ọgbẹni Shọpeju tun ṣe alaye pe asiko ayọ ti de tan bayi o ni ni ikẹhin ayọ ni ti ẹgbẹ Afẹnifẹre yio jẹ. O tun ṣe alaye pe tisisiyi



Oloye Obafẹmi Awolọwọ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

rẹ awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiri ti ti Ijọba Oriṣ ... bayi a ti pe awọn ti mọ iru Ijọba ti akoso rẹ ba ... lare mu.

Alaga ọjọ na tun ṣe alaye pe ki Oṣukuluku awọn ọmọ ẹgbẹ na ni emi is wọ pọ lati ara wọn nitoripe ko si iyato ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ni jakejado ilẹ Naijiria ati pe ... ọkansoso ni gbogbo wọn iṣe.

Ọgbẹni Shọpeju tun kan ... si Ijọba Ologun to nṣe eto akoso Ijọba ilẹ Naijiria bayi nitoripe Ijọba olo dodo ni Ijọba Ologun iṣe ati pe ko si wa ... aderu ni nu ohunkohun ti Ijọba Ologun be ... lati ... ni asiko ti awọn gba eto ako so Ijọba Naijiria bayi.

Lẹhin eyi ni Alaga Obinrin

Nimọta Erufọlahan tun ṣe alaye diẹ lori oke iṣoro ti awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre lọkunrin ati lobinrin ti ri ni ilu Mushin ati pe awọn ko si titorina ba ara jẹ nitori pe nwọn si duro gbọingbọin ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre laiṣe iye meji.

Iyaafin Nimọta tun ṣe alaye lori iya ti nwọn jẹ la ti ... mọta ṣẹhin nigbati ẹgbẹ Dẹmọ nṣe eto akoso ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

O tun ṣe alaye pe akoko ... bayi ... ti de bayi ati pe ohun to ku bayi ni ipada bọ ijọba tuntun ... ti awọn ẹgbẹ ... olododo ti ... lẹhin ati ijọba ologun ba ti eto akoso ijọba na silẹ.

Iyaafin Erufọlahan tun dupẹ lọwọ Ijọba ologun ilẹ Naijiria ... tun ṣe al ye pe ki gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ

Afẹnifẹre lo ni emi ifẹ ati ... at pe awọn si ... jiya sẹhin ... ni asiko ayọ si ti de fun wọn bayi.

Lẹhin eyi ni Alaga ọjọ na ọgbẹni J A Shọpeju si apa kan Basikulu na eyiti Alaga obinrin Iyaafin Nimọta Erufọlahan si ki ... ọgbẹni Agunbiade, Adepitan ... Alaga ẹgbẹ ọdọ ẹgbẹ Ado ... Sanya akọwe eto akoso ẹgbẹ ọgbẹni ... O Sanni, Iyaafin C A Talabi ati awọn miran tun lọ si Basikulu na pẹlu ... iye owo.

Lẹhin ni awọn si Basikulu na tan ni Ọgbẹni B A Apampa lat ilẹ ẹka gige julọ Unifasiti ti ilu Eko ti o si tun jẹ ọkan ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ẹka giga na ... ṣe alaye lori ... ti Basikulu iṣe ati gige ni awọn ti ṣe gbẹ ṣe Basikulu ni ilu Gẹẹsi ati bi o ti ṣe tun wu lọ fun awọn enia.

Ọgbẹni B A Apampa tun ṣe alaye lori isọwọpọ to wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ... ati ... ti a wa yi O tun ... awọn ... to wa si ... ayẹyẹ ... duro ṣin ... ẹgbẹ Afẹnifẹre Ni ... rẹ tan ni Ọgbẹni Apampa wa s Ba ... pẹlu ... Oruko ara rẹ.



Alhaji D. S. Adegbenro

Eleyi ni diẹ ninu awọn enia jankanjinkan to wa sibi ayeye ọjọ na, Ọgbẹni B A Talabi Oloye Adepitan Oloye Arolohun ... Ba yọ Ṣowande Omidan Akin ... Iyaafin C A Bolo Iyaafin M ... Iyaafin Ọmotayọ Odunaro Ọgbẹni R A F ... Ọgbẹni S A Okemakinde ati awọn enia jank njankan miran ti aye ko si gba ti daruko won

WANTED

Apprentice Printers And Advanced Apprentice Compositors
Apply in person to the;

MANAGER
16 Bamgbose Street, LAGOS

## Iwe si Olotu Irohin Imole

### Ẹ tun Awọn Oju–Ọna Ṣe

Bi inu mi ti dun nipa awọn iṣe ribiribi ti Ọgagun ti iṣe Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣe ti mọ si tun nu gbogbo ara ki Fajuyi ku iṣe ni mo si tun nkesi pelu ẹbẹ wipe ki o Jọwọ tete ba wa tun awọn ọna ti o ba jẹ ṣe ati eyiti awọn ko ti da ọda si ki nwọn ba wa da ọda si nitori ewu iku ojiji ọkọ didanu.

Bakanna ni a nfẹ ki nwọn ba tubọ ko ile iwosan itọju alaisan ati ti Alaboyun si pẹlu ọpọlọpọ ogun fun lilo awọn alaisan,

A si lero pe gbogbo irẹ ni Alagba Ologun Fajuyi yio ba wa ṣe ni kiakia ẹ ku iṣẹ o.

Emi ni
TAIWO ADEKUNLE
AWẸ.

### Ile Eko Giga Ti Ilu Awe NKo

Olotu, Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe yin to nun fun ọgbọn ati oya lati kesi awọn Oti lati le ma tọ awọn si ọna ti o tọ lati ma gba nigba ewe wọn eyiti yio fun awọn Obi ni Isinmi nigbati nwọn ba dagba tan nitoripe iwa rere l'oṣhọ enia gẹgẹ bi Imọlẹ ti ọjọ kọkandinlogun oṣu kini odun yi eyiti o lọ bayi pe Ehn ni iwa, A sun iṣu nile gọgọ rẹ nyọ sita, nitoripẹ iwa enia ni yio fi wa han n bikibi ti a ba lọ iwa rere l'Ọshọ enia,

Ti a ba yọ ipin loju, oju ni a fi nhan, ki o le mọ pe on nṣọbun nitori eyi a bẹ ẹnyin Igbimọ ilẹ ẹkọ giga ti Awẹ (Awẹ High School) lati ba wa mojuto ile ẹkọ nitoripẹ ọrọ ti a ngbọ nipa ile ẹkọ na ko ba eti mu rara omi titun ti de ẹja titun ni yio wọ inu rẹ.

Adura mi si ẹnyin to gba Iṣẹ na pe ki Oluwa maṣe doju ti nyin nitoripe Ọba tọ jẹ ti ilu fi tuka ati eyiti o jẹ ti ilu fi toro awọn mejeji ni orukọ wọn yio wa ninu iwe itan.

Nitori eyi mo bẹ ẹyin ọmọde ati agba ki e jeki a tun Awẹ ilu baba wa ṣe, Eleyi paapa jẹ ohun ti o dun awọn ẹgbẹ ọdọ ọmọ ibilẹ Awẹ lati ri pe awọn olowo ati ọlọrọ ilu wa ko si kọ ibi ara si eto ilọsiwaju ilu wa.

Lẹkansi awa ẹgbẹ ọdọ na dupẹ lọwọ baba ẹgbẹ wa Alagba A. A. Amọjẹ fun iṣẹ ribiribi ti o nṣe ni ilu Awẹ, Oluwa yio ran lọwọ Amin.

Emi ni
J. Olu Akintunde
EKO.

### Ogunde O ku orire

Alagba Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi ni aye kekere yi lati ki Ọgbẹni Herbert Ogunde (Elere ati ma le jo ni )ku orire ti Awe ti Ijọba Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun pa ki o ma rin ki o si ma yan kakiri ibiti o ba nwọn lati Orun tẹlẹ ti pa pe ko gbodo ṣe ere lati ki awọn elere wa ṣe nibikiki ni ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria'

Mọ ba Ọgbẹni Ogunde yọ o ku orire o, o ku suru owe Awolọwọ ṣe ti o ṣọ pe ẹniti o rẹrin gbẹhin ni o rẹrin ti o dara julọ',

Emi ni
ỌLAYIDE OGUNGBẸSAN
SHAKI.


### IWE KOṢEMANI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣa AYẸWO fun ara rẹ
KOSEMANI" ni Iwe na, 2/6d pere ni a nta:-
Postage 9d

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria (Leti Ọja Jankara)


# Ẹ Ma Ka Iwe Irohin Imọlẹ


# Iwe Itaja 1966

Idamu owo ha wa fun ọ bi
Abiku ha nyọ ọ lẹnu bi
Ari iṣẹ se ha wa fun ọ bi
Ailera mba ọ ja bi
?

Iwọ le bọ ninu gbogbo wahala aiye wọnyi ti i-o ba ra ninu awọn ohun Ijinlẹ iṣẹdalẹ Yoruba ti a to lesẹsẹ si Isalẹ yi.

1 Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/— di 22/6
2 Iwe Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 4/6 di 3/6
3 Iwe Itumọ Ala ati Ogun Wibẹjẹbẹ 4,6 di 3/6
4 Iwe Egbogi Awogba Arun 20/— di 17/6
5 Iwe Itan Ifa Yiyanrin tite ati etutu ṣiṣe 20/- di 17/6
6 Gbedegbẹyọ Hausa 3/—
7 Iwe Aniyan Irun 2/— di 1/—
8 Turari Iṣegun Ajẹ ati Itaja 10/6 Pangolo 2/6 paketi

Fi Owo ranṣe si

J. O. SAOYINKA
P. O. Box 159
MUSHIN

tabi

9, Iyala Street Oduabọrẹ, Mushin



# Ha Kini Eleyi




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara jus gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ,

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun,

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si danwo; iwọ yo ri bi o tiṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti Iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu ori erin mẹta ni nwọn mu fun ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ile itaja kakiri orilẹ ede yi

Distributor

AMOS GBENLE & BROTHERS
34: Docemo Street Lagos.
6 & 11 Balogun Street West

# Egbe Ọdọ Afẹnifẹre Faramọ Ijọba Ologun Naijiria

EKO: Ninu ipade pajawiri ti awon omo egbe odo Afenifere to wa ni (H Area) ni Eko ni awon fi towo tese fa ... Ijoba ologun ti ile Naijiria eyiti Ogagun agba J T U Aguiyi Ironsi ... re, nigbati awon ise ipade na lowo ni Ogbeni Adebobo Awe, akowe ifirohin si ta egbe odo Afenifere ti ... je, o ye ki awon wa lehin Ijoba ologun Apapo yi, gbogbo ... papa ni je ife inu awon eniyan Orile ede yi.

Ile Naijiria s ti di otun bayi nigbati awon omo ogun gba akoso Ijoba ori le ede yi, a ki nyin ... abo si Naijiria to di otun bayi, o je ife inu awon enia orile ede yi pe ... eniken kan le ma p re to si tubu laisbere ni orile ede yi nis yi gbogbo omo egbe odo Afenifere faramo ... inu awon enia orile ede yi pe, gbigba Ijoba yi je ibere ... se Ijoba ... ati ti ... kumo ... le.

Gbogbo iwa ibi, ifoiro, ihale ... ra eni nikan, iwa yiya eya kan soto ti o ti ba ile Naijiria je yio de opin bayi, ti iwa ... afia pelu ifarayabale ati emi isokan yio ma je ba lo ... omo ile Naijiria,

Igbagbo wa ni wipe, ni gbati orile ede wa ti wa la be Ogagun agba J T U Agu iyi Ironsi ti inu gbogbo enia dun ... po s bit Ti ba ... awon yio se ofin ... tuntun ... fun ile Naijiria eyiti yio so gbo wa ... Olori ... ju ori ti ... wa wu lo ninu igbe aiye tuntun alafia ati idunnu gbogbo wa:

Ba nki Apapo Ijoba orile ile Naijiria ti ... bo si ... aiye tuntun, a ... kesi Ijoba Ologun Apapo ... ri wipe alafia ati ibale okan ... Iwo Orun Naijiria, ki nwon ... obunti o ... won ... ki won si fun won ni ... t iwon nfe nipa ki nwon dibo alafia eyiti ko ni ... pe.


Ogbeni ... k ... de

Ni ipari, a nkesi awon omo iya wa ti o wa ti o wa ni Ipinle Iwo Orun Naijiria ti nwon ti nbinu lori ibo ti nwon di ni ojo ko kanla osu ... kewa ki ... yara tete awo ninu iwa ti koda ra, ki gb gb won gbaru— kut Ijoba Ologun ti ile Naijiria.

S ... ra re gbe, Ogagun agba ... iyi Ironsi ki ... run fun o ... emi ki o le sin awon enia re ase.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Mu suru, ki o fi ori ti lehin wahala ati ... nu, ayo ati idunnu ni igbehin logo Oluwa igb ... hin ... dun

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Sora loni gidigidi nipa mo to wa loni ... o ... si se fi ... mimu se aye ki o ba le si nkan nafani

ARIES (Mar 21 - April 20) Se pelepele n biti o nlo se faji tabi ni ibiti o gbe ba won dawo idunnu, ki o ma ba je ija kiji.

TAURUS (April 21 — May 20) Afojudi ko dara fun o loni ki o si sora nipa Aladura kan o ma ba ti ipa ere ... da ese nla kan si Olorun

GEMINI (May 21 June 21) Alejo obinrin kan nbo wa ki o loni on ni yio si gbogbo ... san ara re kuro

CANCER (June 22 July 28) J ... je ni ... ojoja nyan mase ti ikanju tabi wara se nkan loni nitori ki tole to fi ma mu o

LEO (July 23 Aug 22) M ... se jeki eje tete ma ko si o lori ki o si ... pe lenu ise bi o w ... ni won ni ki o o ba awon omobinrin se ere pa mo.

VIRGO (Aug 32 Sept 23) Ogineta akoko yi ko se, sugbon bi o ba ... yio ma ... so iwo koni ... kan ... ni

LIBRA (Sept 24 ... ct) Tuj ... k ... k o si se ... ra giri, bi o ba w ... pe ... mu ... nu ... ro ko ni d ... n

SCORPIO (Oct 24 ... ov 22 B ... wo fun asiwaju re ki o ma ... a la do re s ... h ... n, ki ... iwaju ... ma ba di ... n

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) ... n gbogbo ojo oni yio je fu ... o ... lo ... ti ... si ki ... o ... le te ... lowo

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Mu a si ise re, mase gbekele awon ore ... ba o se nkan ... bi o ti ... o ni o pe won pelu

GEGGED ARA ILU NKO ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYNAMIREN** TONIKI

ALE-IBI-ALE Egbogi To ki amonu, titu ti gbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mo daju — Agbara ati Agbidan se ... ra agbalagba Okunrin ati Obinrin gbogbo

Bi are ara ba nmu o, ni gbakugba fun wahala tabi ise sise ti o ko le jeun daradara, tabi ki o maio sun da da de okan ... san tabi awon isan ara re gbogbo ki se fun daradara ti emi Breath inu ko ba kunle daradara won ise tabi wahala sise tabi inu awon ailera gbogbo nyin ti ojo ori (age) ba ti koja ogbun ... dun si adorin tabi jube lo mo daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfe lati so ara re di otun ... pata oju re yio si wale ... kete alafia ati igbadun de Bere Dynamiren yi ni Sobu awon :-



Waterloo Medecine Stores
8. Palm Church Street P O Box 333 Lagos
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.
ADEDUN CHEMIT
14, Wakeman Street
ATI NI SOBU
ISB OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA
IBADAN

# Asani Taiwo Balẹ Ijẹshatẹdo Binu Fi Ẹgbẹ Dẹmọ Silẹ

IJẸSHA TEDO—ITIRE:- Aja l nia ni o nba ẹgbẹ D mọ nu ojo m t y fu oṣe imoye omo ẹ b ẹ D m ti nw bi a fi egbẹ na sile ti nwọn si nbọ s nu egbe Af if ni wọn w n Adaj Ijọ a Ible I Ilmọ Afọni h Ijẹta Ible, g n ti awọn ena ti nọn pọ pupọ ti nwọ si bọ s nu ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Ninu iwe ti Bale ti Ijeshatedo ni gbe be Itire Bale, Asani Taiwo, ko ranṣẹ si ile iṣẹ wa ni o ti ṣ l ye pe on gẹgẹ i Balẹ Ijẹsh tẹdo lẹba Itirẹ ti yọwọ yọ sẹ pata-pata kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ pẹlu awọn ẹnionọ, o ni tọkan tokan ni on fi bọ s nu ẹgbẹ Afẹnifẹre.

O wa tun sọ pe, lati igbati Ilero on ti daru ni on ba s lọ s nu igbo eyi ti on le o wi e da Ọlọrun kankan ko le n o ni bẹ ṣugbọn esan ni gbogbo re jasi

O ni awoṛan on jade ni nu iwe irohin to nje West African Pilot ti ọjọ sẹjẹ sa to sọja o wa pari ọrọ rẹ pe t wọ tiṣẹ ni on fi wa ni u ẹgbẹ Afẹnfẹre eyi ti gbogba aiye npe hi UPGA

D SAOLU KIṢE DẸMỌ

Ninu iwe ti gbe i M O Das olu k ni o ti ṣe alaye pe on as f n gbogbo ọmọ egbe Afenifere to wa ni Mush wipe on ko f i igbakan wa ninu egbe Demo ri n ko si kuro ninu egbe Afenifere lati igbati on ti da Aia egbe Afenifere la d ud n diẹ sehin, o ya ẹnu lenu wipe on ti ni ọmọ ẹgbe De o ni

Nisisiyi, mo nso fun awọn ọn wa pelu otito ati fẹ inu mi ni mo si fara mo ẹgbẹ Afenifẹre pelu aṣi waju ẹgbẹ ni Alhaji Adebenro pelu Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolowo gbogbo wa ni ti ba ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ti Dẹmọ, a si ti iyi t to wa nibẹ, o ban gba gba pe ẹgbẹ Afẹnifẹre nikan ṣe ni t ẹgbẹ Dẹmọ jẹ ẹgbẹ ti nda ka ru


# KERE O

Njẹ o ti ni ninu IWE ITAN ODUDUWA to ṣẹṣẹ jade ?

Ha! Kosemani ni Iwe na je fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan iṣedale Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Maṣe jeki nwọn rohin itan Ilu rẹ fun ọ 3/- pere ni. Postage 9d

Tete fowo tirẹ ranṣẹ si:-

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria



# KERE O

ẸNYIN ỌMỌ ODUDUWA

"ỌBA ATERERE KAIYE NKI NYIN" PELU ỌPA AJAṢẸGUN RẸ



## Ọba Alaiyeluwa Oduduwa

Ẹ ku odun Ẹ ku Aleṣẹgun, Ile ko ni le nyin, Ọna ko ni na nyin, Ajinde ara yio ma je fun nyin.

Ẹ mura lati di opo Asia Ọgagun Aguiyi Ironsi mu, Eni to fun ile tẹ bi eni Tẹ'fa, on l T'erọ bi Agogo, O le ọta lugbo, O le oṣi danu, o fi Naijiria lokan balẹ.

Nje o ti ra ninu itan Igbesi aiye Oduduwa ati ti awọn ọmọ rẹ ?

Maṣe jẹ ki nwọn wa rohin re fun ọ, "Kose mani" ni kan inu Iwe na je fun Omo Yoruba Tete lo ra tirẹ toto tiro 3/- pere ni, Postage 9d

F'owo tirẹ ranṣẹ si.—

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria.
Let oja Iinkara




# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,693 WEDNESDAY FEBRUARY 9, 1966 (2D)


## Akowe Banki Kan W'Ewon Odun Mẹta

POTA:— Ni ojọ iṣẹgun tise jọ kini osu yi ni Ad j ile ẹjọ to giga ti ilu Pota pase pe ki Akọwe ile ifi owo pamọ ti "Bank of West Africa Limited" Gadwin Eesimew u yara lọ fi ẹwọn ọdun mẹt jura lori pe ọdaran Akọwe Banki ji owo gbe atipe o fi owo ti ile ifi owo pamọ ṣe tirẹ eyiti o fi ọna ru ji gbe ninu ile ifi owo pamọ na.

Ninu ọrọ Ọlọpa to ba ọdaran ọlọṣa Akọwe ile ifi owo pamo na ṣe ẹjọ ni oti ṣe alaye fun ile ẹjọ lati ọdun 1963 ni ọdaran ọlọṣa na ti ji owo eyiti iye rẹ jẹ pọnun mejileledunrun sile kan ati kọbọ meji (£302 1s 2d) eyiti ise ti ile ifi owo pamọ na

Ọlọpa to ba ọdaran na ṣe ẹjọ tun se alaye fun ile ọjọ na pe Godwin Eejsimegwu tun lo ọgbọn ẹru kan eyiti o fi yi iwe ti nwọn fi nfi iwe ranṣẹ eyiti o gbedo jẹ sile mẹrin ati kobọ mẹta (4/3d) ti ọdaran Ọlọṣa na yi iwe owo na di ṣile mẹrinla ati kọbọ mẹta (14/3d).

Ninu ẹsun meji ti ọlọpa to ba ọdaran se ẹjọ ni Adajọ ile ẹjọ na se paṣẹ pe ki o lọ si ẹwọn ọdun mẹta—mẹta fun ẹsun kọkan eyiti yio je pe gbogbo rẹ ni yio lo pọpọ.

# AWỌN MINISTA ẸGBẸ DẸMỌ NBẸ ẸBẸ FUN ABO

ILORIN:—

Ni ojọ ojọ Bọ ti iṣe ọjọ keta oṣu yi ni awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmo ninu ile igbimọ Asofin ijọba Ipinlẹ Iwọ Or n Naijiria eyiti ẹkan ninu nwọn si jẹ minista ninu eto akoso Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ tele ti wọn fi ṣe atipo si ilu Ilorin ti ko iwe ẹbẹ s Gomina Ologun apapọ ile Naijiria Ọgagun Agi yi Ironsi lati se eto bi yio ṣe da abo bọ emi won ati bi wọn yio tise pada si ilu wọn

Awọn Omọ ẹgbẹ Dẹmo meji na ni ẹgbẹni S. O. A K erele ti ojẹ minista ninu eto akoso Ijọba ti ẹgbẹ Dẹmọ ṣe kọja ni Ipinle Iwọ orun aiiria ati ẹgbẹni D. A. Agbọọla tio tun jẹ ọkan ni nu awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ni ile Igbimo Aṣ fi Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria tẹlẹ.

Ninu ọrọ awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti o lọ ṣe atipo si ilu Ilorin na ni nwọn ti fi ye On we Iroh n wa pe awọn si mọ daju pe emi awọn a ninu ewu pupọ lọwọ awọn ẹgbẹ Oṣelu ti nwọn jẹ ọta si awọn ati pe nitori idi eyi ni awọn se nfẹ ki Ọgagun Aguiyi Ironsi se ọna lati da abo bo awọn.

Awọn ọmọ ẹgbẹ D... tun se alaye pe ... mọ na ni awọn ti jọ ... pọlọpọ iya nduku ọm... ọwọ awọn j... to jẹ pe ... egbẹ oselu eyi ba ... wọn janduku na pe ... awọn dukia awọn jẹ ti ... p lọpọ awọn ẹru wọn kosi lọwọ awọn mọ, Nwọn tun se alaye pe nigbati awọn ọm'ogun Naijiria to gba eto akoso Ijọbaile Naijiria bayi awọn Ipinlẹ na si ti padabọ si ipo ati pe ifọkanbalẹ si ti wa fun gbogbo enia.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ na tun ṣe alaye ninu ọrọ wọn fun oniwe irohin wa pe o jẹ ohun ti nkan awọn loju lati le tete pada si arin awọn enia wọn ni ilu won ati pe ki awọn ọmọ ogun ilẹ Naijiria si da aabo bo awọn lati le ri pe iya ko tun jẹ awọn mọ tabi pe ki ẹmi awọn tun wa ninu ewu.

Ninu iwe ẹbẹ awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ to jẹ Minista ati Ọmọ ile Igbimọ Asofin Ipinlẹ Iwọ Orun tẹlẹ na ni nwọn ti kesi Gomina Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgagun Francis Adekunle Fajuyi lati ṣe eto bi nwọn yio ṣe jẹki awọn ọlọpa pọju kege bi nwọn ti ṣe wa tẹlẹ ni agbegbe wọn lati da aabo bo awọn ati pe ki eto alafia ati ifọkanbalẹ le pada bọ si adugbo awọn.

Ni owuro ọjọ ọjọ Bọ ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi kanna ni awọn ẹgbẹ Alagbelebu Pupa ti ile Naijiria 'Nigerian Red Cross Society" pẹlu iranlọwọ Ijọba ologun Naijiria ni nwọn ti ṣe eto kan lati ko awọn aṣọ ati onjẹ ey ti awọn moto akero si ko awọn aṣọ ati onjẹ na lọ si Iduoko eyi ti iṣe ẹn aala ilẹ Naijiria ati ilẹ Dahomey lati fi ṣe iranlọwọ fun awọn to ṣe atipo si ilẹ Dahomey yi lori ohun to ṣẹlẹ ni orilẹ ede Naijiria.

Bakanna ni rohin tun fi ye wa lati ilu Pọta pe awọn olori ile Ọlọrun meji ti wọn si jẹ Bisọbu ti ijọ awọn awọn C. M. S. Ẹni-ọwọ H. A. I. Afọnja ti ṣe alaye ninu ọrọ pe awọn faramọ ijọba ologun ilẹ Naijiria eyi ti Ọgagun Johnson Aguiyi Ironsi nṣe olori rẹ.

Awọn Bisọbu meji na tun ṣe alaye pe awọn yo si ma gba dura fun eto akoso Ijọba eyiti awọn ọmọ ogun ilẹ Naijiria nṣe bayi ati pe ki nwọn si le ri pe eto akoso Ijọba Ologun na yori si rere

Ẹni Ọwọ Bisọbu Okoye tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ de lati igbati orilẹ ede Naijiria ti gba omiran ninu ọdun 1960 ni lati igba a ni awọn ti ngba adura fun awọn Olori Naijiria.

### IDAJỌ

Nigbati Bisọbu Okeye tun nsọrọ lori Ijọba Ologun ilẹ Naijiria ni o tun ṣe alaye pe awọn si nfẹ ki Ijọba Ologun orilẹ ede Naijiria ṣe ohunti o tọ ati eyiti o yẹ.

Ninu ọrọ ti Bisọbu Afọnja ni o ti ṣe alaye pe o ti jẹ ohun ti o ti to ask ati pe o de oju eyiti o ye ki nwọn ṣe ikilọ fun awọn enia orilẹ ede wa nitori ko si ẹni ti o lọ kọ idajọ si ta b pe ko si e ti o le sa fun idajọ ti Ọlọrun ba fẹ ṣe idajọ rẹ.

Bakanna ni ẹni ọwọ H. A. I. Afọnja tun ṣe alaye pe awọn olori ilẹ Naijiria si jẹ awọn ẹni an ti wa ti ko dura wa lokan ati pe ki nwọn si fi iya ma jẹ awọn enia ti nwọn jẹ talaka tabi al i

## Lati Oju Fwe Keji

oto na gi nwon si le d n owole gbigba ku fun awon oṣiṣẹ,

Ọkan ninu awọn osise Ijọba ti so wipe, Ijọba Sọja ti s eto t n n sisiyi lati d owo ile gbigbe ku f n awọn osisis: yi a gbogbo orilẹ ede yi, ti yio n jẹ wi pe ile gbigbe ni o mu inira wa fun gbogbo awọn osis;.

Onirohin wa kan ran wa leti wipe. Ijọba ti bẹrẹ si mas ko i e fun awọn oṣiṣẹ ni Surulere nw n y o s pari ile na ki o lo di oṣu kẹfa ọdun yi.

Owo p ọku pooku ni awọn oṣiṣẹ yio ma san fun yara mẹta.



J T U Irosi


Printed and Published By Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 25, Branco Street Lagos 9/2/66